ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 835 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 1, — SEPTEMBER 7 1962. KỌBỌMẸJI (2D)

ORO BEHIN YO

# Nkurumah Mu Awon Minisita Re Meji Lo Saja Ile

### O Tun Ti Igba Enia Mole

ACCRA— Ọrọ tun bẹhin yọ ni ilu awọn Aganyin (Ghana) ni owurọ ijẹta ni Alakoṣo Ijọba ilu na, Dokita Kwame Nkrumah, ti o nse eto bi awọn ara ilu na yio ṣe fi on jẹ olori (life President) Ijọba ilu na titi di ọjọ-iku on lọwọ, paṣẹ wipe ki nwọn mu meji ninu awọn Minisita alabasepọ on lọ si aja-ilẹ nitoripe on fura si wọn pe nwọn wa ninu awọn ti o ditẹ lọwọ ninu awọn ti nwọn fẹ fi bombu pa on laipẹ yi. Ẹnikẹta ti nwọn tun mu pẹlu wọn ni Ọgbeni H. H. Kofie-Crabbe, akọwe ẹgbẹ oselu ti o gbe Dokita Nkrumah de aye ti o wa loni ti nwọn npe Covention People. Party (CPP). Orukọ awọn Minisita meji na ni Ọgbeni Ako Adje, Minisita alamojuto ọrọ okere, Ọgbẹni Tawia Adamafio, Minisita alamojuto nkan irohin.

Iṣẹ lọya ni awọn mejeji na ki nwọn to yan wọn si iṣẹ Minisita. Laipe yi ni Ọgbẹni Adamfio ni ỌLỌRUN AWỌN ni Dokita Nkrumah ko tun si ỌLỌRUN miran fun ara Ghana mọ lẹhin rẹ. Ako Adjei ni ọmọl'ọwọ ọtun Nkrumah, on na ni o si ngbero lati mu lọ si ilu Oyinbo ninu oṣu yi fun ipade awọn Alakoṣo Ijọba Agbaiye (Commonwealth Prime Ministers' Conference) ti nwọn fẹ ṣe ni London.

Gbogbo iwe ti Ijọba ilu Ghana tẹ jade lana ni nwọn bẹrẹsi lọgun wipe nṣe ni ki nwọn yẹgi fun awọn oṣelu mẹtẹta na ki nwọn si ku iku-oro nitoripe nwọn fẹ pa Ọlọrun awọn.

Minisita kẹta ti nwọn si nro bi nwọn yio ti ṣe ọrọ rẹ si ni Ọgbẹni Aaron Ofori-Atta, Minisita almojuto

(Wo yoku loju ewe kẹjọ

YORUBA CHALLENGE

SEPTEMBER-OCTOBER 1962

**O Ti Jade Fun Tita.**

Kọ awọn ogbọn nipa: Ohun ti nfa Mọna-mọna

**ati**

Bi a ti ṣe le bọ lọwọ sisan ara

**Iwe oloju iwe 24 yi ko l'ewo.**

**4d** pere ni iwe kan

ORO ENKUARI:

## O Fe Bige Bi Adubi

Lati iwọn bi oṣu kan ti awọn ti bẹrẹsi se iwadi iṣẹ awọn Ajọdaṣẹ mẹfa ti Ipinlẹ Iwọ Orun niwaju Adajọ Coker, ọrọ ẹlẹri kan, Patrick Ọsoba, ti o nse ewọn lọwọ, ti awọn Ijọba ru wa lati ọgba ẹwọn wipe ki o wa jẹri, fẹ jẹ ki eto iwadi na bi Ige b'Adubi lati nkan bi ijẹrin wa nitoripe ni ọtunla ọjọ Aje (Monday) ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Babasalẹ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ni on nlọ Kotu-nla lati lọ ṣe ibura niwaju Adajọ wipe lọya Michael Okorodudu, ti nse alabojuto Ijọba lori Iwadi na ngba awọn apakan. O ni on ti ri nkan dimu daju ki on to sọbẹ.

O ni Okorodudu ko ti sọrọ awọn ọmọlẹhin on kankan ni rere lati ọjọ ti awọn ti bẹrẹ ọrọ iwadi na sọ,

(Wo iyoku loju ẹwe kẹjọ)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABECKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Natbanger ; London

Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20)

Lati bi ojo meta ni o ti gbe ero kan lokan ti eru si mba o nipa nkan na, kosi nkankan. Adun lo eghehin ewuro ni oro na.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Wa ri

tire se lori oro a-feni a-ko feni kan lose yi. Ti o ba je ise olopa tabi ise soja ni on se ire wa fun o.

ARIES (Mar 21-April 20) So

ara re pelu edibikita. Wa ri oju rere lodo awon a'adagbo re. Ojo Satide ti mbo yio dara fun o lati se ipade igbeyawo ati lati se adehun.

TAURUS (April 21-May 20) Mo se ireti iroin aladun kan, boya o le lo si irin ajo paapa. Mase mu oti pupo.

GEMINI (May 21-June 21) Edeaiyede kan a wa larin iwo pelu awon ebi re, ki o se pelepele ki o ma si soro enikan lehin rara.

CANCER (Jun 22-July 23) Awon omo re yio hu'wa ti o ba oju mu ti inu re yio fi dun si won, sugbon iwa okan ninu won a le je ki o binu die. Mase bianu rara igba ohun rere wa fun o.

LEO (July 24-Aug 22) Wa lo Ebun egbon ti Olorun fun o tun anfani awon alabasese re ninu ose yi, sugbon ki o sora ki o mase so gbogbo nkan ti o mbe lokan re tan fun won nitoripe nwon yio ja o tile.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Awon enikan nsoro re lehin, ma fara sii nitoripe nwon ko le ri iran kan tu lara re, ola re a si ma lo soke.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Sora lodo awon obinrin lose yi nitoripe nwon a fi nkankan lo e ti yio mu ki o padanu owo die. Ojo Alamisi, Jimo ati Satide je awon ojo rere fun o.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Gbogbo wahala re ko ni bo si asan sugbon a nira die lati tele eto ti o se sile lati ehin wa. Je gbogbo re lo jeki okan re bale nitoripe ilosiwaju wa fun o.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Oro ebi tabi tawon omo re a je nkan ti yio gba o lokan pupo sugbon ki o mase se ise-agbara pupo.

CAPRISCORN (Dec 23-Jan 21) Sora pelu a nse igberaga; iwa re ni yio fun o lorire.

# Balewa Ni Akintola Si Ni Olotu Ijoba Ipinle Iwo Orun

NI ojo Aje tise ojo ketadinlogbon osu yi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Ijoba Apapose Nigeria pe gbogbo awon olotu iwe-irohin ti o nte iwe l'Eko ati kakiri gbogbo agbaiye sinu ile re ati ba won soro lori bi gbogbo nkan ti nlo ni ilu si.

Ninu idahun kan ti Alakoso na da okan ninu awon Olotu iwe-irohin na lohun ninu ibere won wipe nje o le pe Oloye Samuel Ladoke Akintola, ti nwon fi igba kan ro loye Alakoso Ijoba Iwo Orun, pada si ipo re gegebi Alakoso (Premier): o ni beni, nitoripe nwon ti gbe ejo Alakoso na lo si Kotu, awon adajo ti o se ejo na ni yiyo ti nwon yo Oloye Akintola loye Alakoso ko tona rara.

Oloia Tafawa Balewa ni nitoto gbogbo wa ni a mo wipe bi oro pajawiri ba de ba Ipinle Ijoba kan idibo ni o ye ti o leto ki nwon fi yanju re.

## OloPo'nia

Alhaji Tafawa Balewa ni bi Oloye Akintola ba tun pada sori aga Alakoso na, bi Ile Igbimo Asofin Ipinle ba si gbe ija tako o, a je wipe awon Olotu Ijoba Apapose a tun lowo ninu oro won na. O tun se alaye siwaju lori awon ti nwon ha iwe ihamole fun ti nwon ko ti da won sile.

Alakoso Ijoba Apapose na ni o tile ye ki awon omo egbe Afenifere (AG) ma yangan ki o nwon si rlase igberaga nitoripe nwon je olopo-enia ni Ipinle na, iyen ni o si je ki awon omolehin won si po pupo ninu ihamo na di isisiyi.

# O Nfi Igbadun Sayo



Aworan yi ni igbati Akowe Ijoba Gesi fun awon Ijoba Alabasepo, Ogbeni Duncan Sandys, nigbati o mba awon omo elere kan, ni adugboti nwon ti yan an sile Igbimo Asofin, mba won fi bolu afowogba se igbadun ki o to pin ebun fun awon ti ayo won je.

ALHERI OMO HAUSA NI:

# Awa Hausa Ko Ni Ikorira

## Ile Iwe

Oyẹ, o si ni ẹtọ lati jẹ ki nsọ itan ara emi ti mo nfẹ sọrọ si inu iwe Eleti-Ọfẹ ninu ọsẹ yi fun ẹnyin ti ẹ fẹ ka a. Baba ti o bi mi lati ilu Zaria ni o ti wa pẹlu iya mi ki nwọn to wa fi Abẹokuta ṣe ijoko. Ni Abẹokuta ni nwọn si bi emi ti mo fẹ ba yin sọrọ lọsẹ yi si ni iwọn nkan bi ọdun marundinlogoji ni adugbo kan ti nwọn npe ni Mọkọla ni Ibẹrẹkodo.

Iya mi amala ni o nta, nwọn a si ma pe e ni Iya-tuo; baba mi jẹ a-ta-malu. Ko nṣe ẹran malu nikan ni baba mi nta, o ma nta ẹran agbo pẹlu.

Ile Kewu ni awọn obi mi yi kọkọ ran mi lọ; o si pẹ pupọ ki nwọn to mọ riri pe awọn ni lati ran mi lọ si ile iwe. O to ile iwe mẹta ti mo lọ ni Abẹokuta na. Gbogbo igba ti mo nlọ si ile iwe awọn ọmọ Yoruba ni mo mba rin. Mo ti to ọmọ ọdun mẹdogun ki nto lọ mọ ilu awọn iya ati baba mi ni Zaria.

## Ile Ogbon

Nwọn ni bi enia ko ba de oko baba ẹnikan ri, a mi sọ wipe oko baba ti on ni o tobi pupọ ju. Nigbati mo de ilu Zaria ni mo to mọ wipe ilu Ẹgba ko nṣe yẹyẹ nipa a-nṣe-ilu (politics), nitoripe ti awọn igbimọ ba nṣe ipade ni ilẹ Igbimọ ni Ake, emi wa ninu awọn ọmọ ile iwe ti o mọ nsaba lati wo wọn.

Ọba Alake a joko, awọn Ọba Olowu, Ọba Agura ati Ọba Ọṣinlẹ ni Oke-ọna nwọn a si tun joko tẹle e. Gbogbo awọn ti awọn ara adugbo yan ni aṣoju wọn a tun pe ṣiba-ṣiba sibẹ. Olukuluku a si ma fi taratara sọrọ nkan ti nwọn ba wa sibẹ.

## Ife Owo

Nkan ti o ya mi lẹnu wipe ni aiye igba na ifẹ owo, anikanjọpọn ati igberaga ko si. Gbogbo awọn ti nwọn yan si Kansulu (Igbimọ) na nṣe tifẹ-tifẹ, ẹnikan ninu awọn tisa ti o ṣe oluko fun mi ri wa nibẹ nigba na.

Boya ẹ le wipe ọtọ ni nkan ti nwọn ni ki nsọrọ lori rẹ, itan bi nwọn ṣe bi mi ni mo nsọ; ọrọ lo ko moro wa.

Ki a sọ gasikiya, sugbọn awọn ọmọ igba ti a wa yi ni ọrọ gasikiya kan ko si nibi kan, ko si Ipinlẹ kan ninu Nigeria ti a wa yi, ti o le sọ wipe on ko ri ẹkọ kan ninu bi nwọn ti nṣelu lati ọdọ awọn oṣelu Ẹgba.

Nitotọ awọn Ẹgba mọ bi a ti nṣe eto ilu. Ẹkọ ti mo ko lọdọ wọn ni o fi ọna han mi lọdun ti mo lọ si ilu awọn iya ati baba mi ni Zaria.

Lọdun ti mo de ilu Zaria iwa awọn enia obi mi ko n mi lara rara, nitoripe ni ilu Abẹokuta (ilu Ẹgba) awọn Yoruba ti nwọn fi wa pelu wọn ti nsọ fun wa wipe ni IGBA-GBO-GBO, ki A MỌ BỌWỌ FUN AGBALAGBA. O ko gbọdọ ṣe igberaga ninu ipo-kipo ti ẹ ba wa.

Ko si ọrọ pupọ nipa nkan ti o nlọ ni ilu Nigeria ti awa ọmọ Hausa ko mọ nisisiyi. Mo gọ ọrọ mi kuru ni, nitoripe nko fẹ ko iwe sinu iwe Irohin Eleti-Ọfẹ ti yio da ilu ru rara.

Mo tun wi, Nko fẹ ko itan sinu iwe Irohin Eleti-Ọfẹ ti nwọn yo ka ti o le dabi ọrọ ti yio da ilu Nigeria ru, nitoripe mo ti gbọ wipe kakiri ile aiye titi o fi de ilu Ghana ni nwọn nka iwe na.

## Orin Ote

Orin kan-nwa wa ti ẹnyin Yoruba mu nkọ ti ko yẹ ki gbogbo enia ma gbọ. Orin na ni:

Kaka ki a dọbalẹ fun Gambari,
Ki a roju, ki a ku.

Eniti o ba sọ wipe awa Hausa ko ni nwọn fi orin yẹn ba wi, eleware puro ni, ko si ododo ninu ọrọ re. Ṣe enia ni nkọ ni pe ki a gọ, enia ni o si nkọ ni wipe ki a gbọn.

Awa Hausa kọ ni a da a laba wipe ki nwọn pin Ipinlẹ Iwọ-orun si ọna meji nitoripe ko si irẹ kan ti pinpin si meji na le ṣe fun wa.

Ọmọ ilẹ Yoruba ni o sọ, ninu ile Igbimọ wipe on fẹ ki nwọn da Ipinlẹ Iwọ-Orun si meji. Awọn Yoruba na ni nwọn nda a laba nisisiyi pe ki nwọn le ta oju-ala Ẹko siwaju si ki o le de ilu ti nwọn npe ni Ota lọna Abẹokuta.

## Ile Ole

Gbogbo ara ilu Nigeria

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

"ERUKOBODO" NI:

# Yoruba, Asiko To E Parapo

OLOTU, gbarai laye ninu Iwe Irohin rẹ lati ke si ọmọ Yoruba nile, loko ati nilu okere, nitoripe, asiko to fun wa lati parapọ ṣe ohun rere silẹ de awọn arọmọdọmọ wa to mbọ lẹhin.

Mo fẹ ki ẹ mọ daju pe ninu gbogbo orilẹ ede ti Olodumare da sile aiye, bi ọwọ awọn alawọ funfun ba yọ kuro, ko tun si orilẹ ede kan nile awa alawọ dudu to ni ọgbọn ju ọmọ Yoruba lọ, sugbọn, bi ọgbọn ati lakaye wa ti pọ to, a ko lo fun irẹpọ ara wa, bikoṣe wipe, ki a ma lo fun ẹta-inu, tabi ẹgan. Bi o ba ṣe wipe bi ọmọ Yoruba ti ni ọgbọn to, ni a nfi ọgbọn na wa irẹpọ si arin ara wa, bi a ti kere to larin orilẹ ede miran yi, kiba ti si orilẹ ede kan ti yio le fi ọwọ rọ wa sẹhin ninu ohun kohun, sugbọn "Ọmọde lọ'gbọn agba l'ẹgbọn (eyi ni wipe, iwọ ko ju mi, emi ko ju ọ) ti a ti fi da Ilẹ Ile-Ifẹ ni ọjọ kini, lo nfa ajumọ ṣe pọ ọmọ Yoruba sẹhin.

Ọmọ Yoruba! asiko to lati fi ọgbọn ati lakaye ti Olodumare fun wa, wa irẹpọ ododo larin ara wa, nitoripe, gbogbo wa ni a la oju wa silẹ, ti a nri gẹgẹbi ile aiye ti nlọ; ṣe ẹ nroju aiye l'ode, tabi, ẹ ko ri?

Ẹnyin ọmọ Yoruba lo npa l'owe wipe "Isu parapọ, o di iyan, agbado parapọ, o di ogi' l'ode ti oni, awọn Hausa para wọn pọ nwọn di olori; Ibo para wọn pọ, nwọn di oriṣa. Kini awa ọmọ Yoruba ṣe da nimu iwa ọdalẹ; ṣikisi, ẹgan, tẹmbẹlẹkun ati kẹnimani nilẹ Nigeria?

## E Ranti Ehin Ola

A mọ wipe, awa ti a mbẹ l'ode aiye loni, ti ngoke agba, sugbọn awọn arọmọdọmọ wa ti o mbọ lẹhin nkọ? Tabi, ẹ ti gbagbe wipe, "ọpa ti a ba gbe le ejika ti ẹhin loju."

Ọmọ Yoruba! ọrọ to de lẹ yi, ki iṣe ọrọ yẹyẹ tabi ọrọ awada. Ọrẹ yi ti kuro niti ọmọ ẹgbẹ ọlọpẹ ni mi, tabi ọmọ ẹgbẹ alakuko, ẹ jẹki a finu konu, ki a fi ikun lukun, ki a ṣe ara wa ni oṣuṣu-ọwọ, ki a le ri ohun fi gba ọpọlọpọ iya ati ọpọlọpọ iwọsi kuro lọna fun awọn arọmọdọmọ wa ti o mbọ lẹhin.

Ni a sọ yanju ọrọ mi

(Wo iyoku loju ewe keta)

Advt. No. 151

Ṣe o ti lọ paro owo atijọ ọwọ rẹ Si OWO TUNTUN ti ile Nigeria? O le paro

OWO PEPA Ẹgẹnsi l'ofẹ titi di ipari oṣu SEPTEMBER ti a wa ni inu rẹ yi.

Ti owo ṣile ati awọn isongbe rẹ di ipari oṣu DECEMBER.

# ELETI-OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos.     "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468     Phone 23370.

VOL XIV. No. 835. SATURDAY SEPT. 1, - SEPT. 7, 1962


# Ile Iwe Ofe

IROHIN aladun kan ti a gbọ ninu ọsẹ yi lati Ipinlẹ Ariwa ni pe awọn olotu Ijọba na fẹ da ile iwe ọfẹ sile fun awọn olowo ati talika ni oke odo Ọya. Awa oni iwe irohin Eleti-ọfẹ a ba awọn aladugbo wa na yọ, a si ki nwọn ku orire," sugbọn ede ọrọ kan ti Alhaji Isa Kaita, Minisita alamojuto eto ẹkọ Ipinlẹ na sọ ninu ile Igbimọ awọn asofin ni Kaduna nipa ọrọ ile iwe ọfẹ na ni ko ye we si.

Nwọn ni Alhaji Isa Kaita ni awọn ṣe akiyesi wipe awọn ọmọ awọn ni Ipinlẹ na rẹhin pupọ ninu ẹkọ-iwe kika, sugbọn nisisiyi awọn tiṣe tan lati pese ẹkọ ti yio ba oju mu fun awọn, ti awọn na yio si di ẹniti o ni awọn olukọni, onisẹ ọwọ ati akọwe owo jaburata, ti Ipinlẹ awọn yio si bọ lọwọ awọn ALEJO ti o nwa ṣe iṣẹ lọdọ awọn.

Tani awọn alejo na ti Minisita yi mba wi? Gbogbo wa ni a mọ wipe o ṣe Yoruba ni, tabi Hausa ni, tabi Ibo ni, fọkanna ni gbogbo wa ninu Ijọba Apapọse ilẹ Nigeria. Kinni o wa fa ede awọn alejo ti Minisita yi nsọ?

Bi a ba nfẹ irẹpọ ati alafia fun ilu wa, o yẹ ki a ṣe ara wa ni ọmọ iya kanna, nitoripe ti a ba jọ na pọ nyẹ lọ nyẹ ni.


DON'T · WASTE



E ma fomi sofo mo


# Iwe Si Olotu

## Omo Obanta, O Se

Olotu,

Ẹ gba mi laye lati kansasara si Ọmọ Ọbanta fun iwe ọrọ pataki ti o sọ sinu iwe Eleti-Ọfẹ ni aipẹ yi. Nitotọ ko si ilu ti iwa abosi ko si sugbọn ti awa Ijẹbu ni o peleke.

Nibiti rukerudo ba ti bẹrẹ awa ni a nṣe iyalode rikiṣi, awa na si ni balẹ tembelẹkun. Awọn ọmọ Ijẹbu ti ewe agbo rẹ ko ba ti pe ni yio sọ wipe ki nwọn ge Ipinlẹ Iwọ-Orun si ọna meji nigbati nwọn ko ge Ipinlẹ Ila Orun (ti awọn Ibo) ati Ipinlẹ Ariwa (ti o jẹ ti awọn Hausa), si mejimeji.

Onigba ni o npe igba rẹ ni akara ti a mba fi ko ilẹ. A dupẹ lọwọ Ọmọ Ọbanta.

Emi ni,
D. Odulaja

Ijẹbu—Ode.

## Oro Arun Yapa-yapa

A dupẹ lọwọ Olofintoto yin fun ikilọ ti o ṣe sinu iwe Eleti-Ọfẹ laipẹ yi nipa egbogi kan ti nwọn npe ni Thalidomide tabi Distaval ti o njẹ ki awọn aboyun bi abami ọmọ, ti o nya wọn lapa, ya wọn lẹsẹ,

Ẹ jowọ, ẹ ba wa tun sọ fun Olofintoto na ki o jọwọ ki o tete ma ba wa tun tẹ iru irohin bẹ jade nigbamiran nitoripe iru itan bayi ti a nri ka ninu iwe Eleti-Ọfẹ na ni a ṣe ngbedun rẹ.

Mo dupẹ aye ti ẹ gbami.

Emi ni,
Alagbado     L. A. Salakọ,

## Oro Ori Didaru Ni Ilu Oyinbo

IBADAN—Dokita T. A. Lambo, dokita ọjọgbọn ti o nwo awọn alamodi ti ori wọn daru ni ile alaisan Aro ni Abẹokuta ni awọn ọgọrunlemẹrin akẹkọ ni ori wọn daru, ti ọrọ ko jọ were, ti ko jọ asinwin ninu awọn ọmọ ti nwọn ran lọ kọ ẹkọ ni ilu Oyinbo. Dokita Lambo ni awọn Ipinlẹ Iwọ Ọrun ni awọn ọgọrun-le-mẹrin na ti wa. Ti awọn Ipinlẹ miran wa lọtọ.

Dokita Lambo wa ni ilu Oyinbo nisisiyi o si nṣe

(Wo iyoku loju ewe karun)


**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask**

**& Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Oni Alapako

MO gbọ wipe Ọgbẹni Ọlalekan Ọnatade ko ti pari itan ti o nkọ nipa ilu Eko, ti o npe ni "Eko Akete Ile Ọgbọn." O dabi ẹnipe ẹmi Ayiluka tun fẹ ṣe ofofo kan fun nyin nipa itan ilu Eko na, nitoripe a ki gbọn tan.

Mo ṣe iranti wipe laipẹ yi ni Ọgbẹni Ọnatade sọ itan diẹ bi awọn Ẹgba (lati ilu Abẹọkuta) ti nma wa lati ta ọja wọn l'ebute Alakoro ati ni Olowogbowo l'Eko ni aiye atijọ, ṣugbọn ọrọ kan ni mo tun fẹ fi si nyin leti nisisiyi nipa ọrọ ilu Eko na. Iyẹn ni nipa ọrọ awọn Egun pẹlu awọn ara Eko.

## Egun Ko Mokan

Nigba aiye atijọ ti awọn ara wa ti a npe ni Egun lati Badagri ba wa si ilu Eko, epo ati ekurọ pẹlu ewe taba ati ọti lile ni nwọn ma ngbe wa ta ni Eko, sugbọn ti nwọn ba fẹ pada si ilu wọn, nwọn ma nṣe ọrọ na ni Oyinbo fẹ lọ, ti o nya'gbẹ s'aga.

Ni ebute Isalẹ-Eko ati ebute Olowogbowo ni Alakoro ni nwọn ma ngunlẹ si, ti nwọn ma nso ọkọ wọn mọ. Lẹhinti awọn alejo wa Egun yi ba ti ta ọja wọn tan, nwọn a ma wa awọn ọmọ t' nwọn yio gbe kri fun awọn Oyinbo Faranse ti nwọn wa ni ilu wọn.

## O Mba Won Selu

Ọpọlọpọ ọmọ ni ni nwọn si ti fi ọna bayi wọ lọ ninu odo Ọsa, sugbọn lọjọ kan ni ọwọ tẹ ọkan ninu awọn Egun ti o nhu iru iwa bẹ ni Isalẹ-Eko: nwọn mu u lọ si ile ọba ni Iga Idunganran. Ọba ti o wa lori oye nigbana tẹ ç lọda, o si sọ orukọ rẹ ni AKỌSINU. On ni o ma nṣe iranṣẹ Ọba ni Iga Idunganran latijọ.

Ẹnyin ọrẹ mi Egun, nko ba nyin wi o, ọrọ lo lọ bẹ o.

## Adele Nse Nkan

Mo gbo wipe Ọba wa, Mudansiku Adele, ọmọ Buraimọ, ti fi iwe oye ranṣẹ si awọn gbajumọ mẹta l'Eko, o si sọ ọkan loko si Dokita Adekoye Majekodunmi, Adele-Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan. Awọn gbajumọ mẹta ti ilu Eko ni Dokita (Adajọ) G. B. A. Coker, alaga Oluwadi ti o nṣẹ iwadi lọwọlọwọ ni Eko nisisiyi: ẹnikeji ni Ọgbẹni J. Modupẹ Johnson (Minisita ti gbogbo yin mọ adape orukọ rẹ ni (J. M. J.), ẹnikẹta ni Ọgbẹni W. Balogun ("Igbalaiye") ọkọ Muniratu ẹniti a npe ni "Wundia Offin" ni Oke Arin.

Mo gbọ wipe oye Asaju Eko ni nwọn fi Ọgbeni Balogun jẹ. Oye a mọ ori o, ṣugbọn ki Ọba Adele maṣe gbagbe oye temi na nitoripe mọkan mọkan loye kan.

Oyekanmi ni orukọ ti mo njẹ.

## Olorun Enia Dudu

Mo gbọ wipe ki ọdun yi to pari ao ti ni Ijọ Ṣọsi Alawọdudu ati olori Bisọbu. Eyi wa mu mi niran ologbe ara ilu wa kan ti o da isin Ijọ kan silẹ nigba kan ti a npe orukọ Ijọ na ni ISỌLARIAN. Awọn ara Eko npe e ni Ijọ Adulawọ.

Sugbọn Ijọ Adulawọ ti mo mọ wipe o gba iyi kakiri agbaiye ni Ijọ Ọrunmila. O gba iyi, o si gba ẹyẹ. Ọlọrun ko dẹlẹ fun Baba-abọrẹ ologbe Okuyiga ati gbogbo nwọn ti o sa agbara wọn lati jẹ ki a mọ wipe awa enia dudu ni ọna ijọsin ti wa.

A bọru bọye! a-bọye bọṣẹ!!

## Ọro Ori Didaru Ni Ilu Oyinbo

(O bẹrẹ l'oju ewe kẹrin)

iwadi larin awọn ọmọ akẹkọ ilẹ wa lati mọ nkan ti o ndun wọn lọkan ti ori wọn fi ndaru.

Oni irohin wa ni dokita yi ti ṣe iru iwadi bayi ri ni nkan bi ọdun marun sẹhin. O kọ bẹrẹ iwadi rẹ na lọdọ awọn akẹkọ paapa, ki o to tun lọ ba awọn ti nwọn yan sinu iṣẹ lati mọ wa anfani awọn ọmọ akẹkọ na.

Lẹhin eleyi a lọ si ilu Amẹrika ki o to pada si ile lati jọ si ilu ti nwọn npe ni Nairobi lati lọ ba awọn ọjọgbọn jiroro nipa ọrọ aisan ti o nda ori ọmọ enia ru kakiri agbaiye.


Adst. NO. 134

NOTICE

NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions :-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting forcing dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of :-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-

The Secretary
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are fowarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962



# Awa Hausa Ko Ni Ikorira

(O bẹrẹ lọju ewe kẹta)

mọ nkankan, iyen ni wipe awa Hausa ko ni ọkanjua. A ko fi igba kan wipe ninu ile-pẹtẹsi ti ẹ npe ni "ile gogoro" nisisiyi ni a fẹ kọ. Ọkanjua owo, ọkanjua ki a ko dukia jọ ni o fa gbogbo ọrọ ti o nja ranyin ranyin nisisiyi ni Ipinlẹ Iwọ orun.

Ni ti gasikiya awọn Yoruba fẹran owo pupọ. Ọpọlọpọ wọn ni nwọn ti sọ owo di Ọlọrun ti nwọn nsin. Ogunlọgọ awọn oṣelu Yoruba ko le ṣe nkankan fun ọ lọfẹ afi ti o ba jẹ wipe nwọn yio ri nkan ponla nibẹ.

Iranṣẹ ni awọn oṣelu jẹ fun awọn ara ilu, ṣugbọn ki ṣe bẹ lọdọ awọn oṣelu Yoruba. gbara ti nwọn ba ti wọ ile Igbimọ aṣofin, nwọn a mọ fẹ foo faa. Ijẹkujẹ a da'gbada fun wọn, nwọn a wa di ọga lori awọn ti o ran wọn ni aṣoju sinu ile Igbimọ na.

Awa Hausa ko ni oṣo, a ko si ni aje, a ko wipe ki ti ẹnikan ki o mọ dara; a kiṣe anikanjopọn. Boya iyẹn ni o nran wa lọwọ ninu gbogbo alamọri wa, Ọlọrun nikan ni o le sọ. Sugbọn bi iya ko ba jẹ ọmọ Yoruba nwọn ki mu ogiri si ọro ara wọn.

Alheri yafi mugun nta.

ọmọ Yoruba kan, ti o jẹ oguna gbongbo ninu ẹgbẹ Alakukọ (ẹgbẹ Ibo) ni igboro Ilesha ṣe apejuwe, bi alagba yi ti ṣe jẹ Alakikanju to ninu ẹgbẹ na, nigbati o to asiko to yẹ ki nwọn sọ Alagba yi di Alakoso ẹgbẹ na, bi o kanran ki ẹgbẹ na fi ẹgbọn mi yi j'oye baba-oke babaisalẹ ẹgbẹ na ni oye ti nwọn fi jẹ.

## Ebiti Pa a

Kilo ra a? Ibo ko gba ki ọmọ Yoruba di Alakoso le wọn lori ni, Bi iru iwa yi ti ṣe wa larin Ibo, bẹna ni o wa larin Hausa, ṣugbọn, 'Ijẹkujẹ ati Irinkurin ko jẹki awa ọmọ Yoruba mọ inu Odo ti a ndọra si."

Nipataki ọrọ mi, mo ke si gbogbo ọmọ Yoruba, ẹ jẹki a jinna si iwa ijẹkujẹ ati Irinkurin, bi a ba ni igbẹkẹle ododo si Ẹleda wa, ti a si ni irẹpọ ododo larin ara wa, ni alai ko ṣe iye meji, bi Oluwa ba fẹ, ao ni agbara to lati le ṣe ohun rere silẹ de awọn ọmọ wẹwẹ to tun mbọ lẹhin.

'Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi, bi o ba de inu rẹ ni yio di odidi"' Yoruba! O dọwọ yin o.

## E ma Ka Iwe Eleti-Ofe Fun Irohin Ti Nigeria Ati Ti Gbogbo Agbaiye.

# Yoruba, Asiko To E Parapo

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

"kosi ibi ti ẹṣẹ kosi, tilẹ wa lo peleke" bi rudurudu ti mbẹ nilẹ Hausa to loni, ọmọ Hausa ko fi ara wọn silẹ, a ni, bi ede aiyede ti pọ to nilẹ Ibo loni kosi ọmọ Ibo kan ti o jẹ k'ehin si ara wọn. Ọmọ Yoruba! E jẹki a pa iwa ọkanjua; ọlẹ ati ole ti si apakan, ẹ jẹki a parapọ fi ọgbọn wa ṣe ohun rere silẹ, ki awọn ọmọ wa, ko ma ba di ẹru-idile Orilẹ ede miran lẹhin ọla.

## Ago To Gbon Sasa

Ọmọ Yoruba! Nko s'ọrọ mi yi fi wa ọmọ kun ọmọlẹhin Oloye Awolọwọ, bẹni, ki iṣe wipe mo nsọ ọ fi le enia kuro lẹhin Oloye Akintọla, ohun ti mo fẹ ki ọmọ Yoruba mọ ni, owe awọn baba nla wa kan to sọ wipe:- "Ọrẹ-kiti-kiti Iyekan-kata-kata, ni ọjọ ti Ọrẹ kiti-kiti ba ku, Iyekan kata-kata ni yio gbe e sin" Itumọ owe mi yi ni wipe, Iyekan kan ni Hausa; Iyekan kan ni Ibo, bẹni Yoruba duro fun Iyekan kan. Iyekan mẹtẹta ti mo ka silẹ yi, ọrẹ ni nwọn jẹ fun ara wọn, bi Iyekan ti Hausa ko tile ṣe ohun kan ko gba iyi larin Ibo, bẹni Iyekan Yoruba ko le ṣe ohun ko gba iyi larin Hausa.

Ki ohun ti mo nsọ o le ye yin, ngo fi ti Ọgbẹni

## Polowo Oja re Sinu Iwe Eleti-Ofe


CARSON PAINTS AND VANISHES









SOLE AGENT:
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

STORM OVER OSOBA

# Awo To Go To Court

## He Says "Okorodudu Is Partial"

**(By Our Roving Correspondent)**

LAGOS—I was informed last night by some members of Action Group of Nigeria that their leader, Chief Ọbafẹmi Awolọwọ, who is appearing for himself as counsel at the Coker Commission may likely swear to an affidavit in the Federal Supreme Court this coming Monday to set out some facts to show that Chief Michael Okorodudu, Q.C., Official counsel to the Commission, has no right to be there as a counsel.

Chief Okorodudu was as far back as 1957 Commissioner for the Government of Western Nigeria in the United Kingdom.

Chief Awolọwọ told the members of the Commission that Okorodudu was trying to use the Inquiry as an opportunity to show his (Okorodudu) personal animosity against him. Moreover, the Chief added, there were some facts in their favour which are being held back before the Inquiry.

### Not Proper

Another lawyer who is battling hard for removal of Chief Okorodudu as counsel for Coker Commission was Mr. Godwin Nzegwu. He said there was a personal element "which makes Chief Okorodudu not to be the proper person to be sitting there".

Mr. Nzegwu said Chief Okorodudu was wasting the time of the Commission by calling Chief Osoba to come and give evidence, Osoba has been sentenced in law Court and "this is not a higher court for retrying Osoba's case."

READ

And Advertise In Eleti-Ofe Weekly News Paper

## Nigerian Ministers' Interest In British Local Government

LONDON—The four Eastern Nigerian Ministers now touring Britain as guests of the Commonwealth Relations Office, spent over two hours discussing local government administration with officals and councillors at Alcester, Warwickshire, learning how the district and its 16,000 people are governed, how the rates are collected, the services run and the amenities provided.

The four Ministers are Chief Douglas Jaja, King Jaja IV, Minister of State, Premier's Office; Mr. J. M. Echeruo, Minister of State, Finance; Mr. Philetus Warmate, and Mr. Daniel James Edoho, Provincial Commissioners of Yenagoa and Uyo Provinces.

The Clerk to the Council, Mr. J. F. Smith, showed his visitors round the town, and took them to a new housing estate near the town centre, where over 300 of the 1,350 houses owned by the Council have been built, with shops, new council offices and a community centre.

"The Ministers thought this estate was delightful and were impressed by the open spaces and playing facilities provided for the children," said Mr. Smith.

Later the Ministers were entertained to luncheon by the Chairman of the Council, Councillor S. H. Pritchard.

During some days spent in and around Coventry they are visiting the Massey-Ferguson agricultural machinery factory, touring a mixed farm, seeing milk bottling and juice bottling plants. They will also visit the Shakespeare Memorial Theatre at Stratford-on-Avon to see a performance of "Measure for Measure." They will be conducted on a sightseeing tour of Coventry's new city centre and the new cathedral srecently consecrated in the presence of the Queen.

DAGENITE

BATTERIES

*give you a longer run for your money!*




Sole Agents & Distributors for Nigeria.

LEVENTIS MOTORS LTD.

Lagos, Apapa, Ibadan, Kaduna, Kano, Jos, Port-Harcourt, Aba.

# Awon Ojogbon Mejo Kowe Si

## Balewa Lori Oro Akintola

IBADAN— Awọn ojogbọn Olukọni (Professors) mejọ ti ile-iwe giga julọ ti nwọn nkọ ni lẹkọ ni University College Ibadan ati University Ile Ifẹ kọ iwe ikilọ kan pataki si Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọṣe Nigeria lori ọrọ ti o sọ fun awọn Olotu iwe-irohin l'Eko ninu ọsẹ yi pe on tun le da Oloye S. L. Akintọla pada saye rẹ gegebi Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun. Nwọn ni awọn bẹẹ ki o maṣee rara ti o b a ... fẹ alafia awọn ara ilu.

Awọn ojogbọn mejọ ti nwọn kọ iwe-ẹbẹ na ni Dokita S. A. Aluko, Dokita A. A. Fayẹmi, Dokita T. O. Fayiga, Dokita I. Odumosu, Dokita D. F. Ojo, Dokita H. A. Oluwasanmi ati Professor V. A Oyenuga.

Nwọn ṣe alaye ri kikun ninu iwe-ẹbẹ wọn na wipe lati pe Ijọba atijọ pada lai di ibo ki nwọn mọ ọkan awọn ara ilu nipa awọn ti nwọn fẹ ki nwọn ṣe aṣoju awọn ninu Ile Igbimọ aṣofin, jangbọn ni ọrọ na a da sile ni Ipinlẹ na.

Nwọn ni lati igbati rukerudo ti bẹsilẹ ni Ipinlẹ na, ni gbogbo eto Ijọba ko ti lọ dede mọ. Gbogbo owo iranlọwọ ti nwọn ma nfun awọn Ijọba Ibilẹ (Local Goverments) ni nwọn ko ri gba mọ, ọpọlọpọ wọn ni ko si ri nkan fi san owo fun awọn oṣiṣẹ wọn. Awọn ọba ati ijoye paapa ko ri owo-oṣu wọn gba dede mọ.

Gbogbo ibi iṣẹ ti nwọn ti jẹ oluranlọwọ awọn iṣẹ Bọdu ati Ajọ'a'ṣẹ (Boards and Corporations) ni nwọn ti da ogunlọgọ awọn oṣiṣẹ wọn silẹ ti awọn ti ko riṣẹṣe si kun ilu.

Awọn ojogbọn na si tun fi ọrọ ye Ọlọla Balewa wipe a jẹ nkan ti o ba oju mu pupọ, a si tun gbe on aiara niyi niwaju awọn ẹlẹgbẹ rẹ, ni awujọ g b o g b o awọn Alakoso Ijọba Agbaiye (Commonwealth Prime Ministers' Conference) ti nwọn fẹ ṣe ipade ninu oṣu yi ni ilu Oyinbo, ti o ba le ṣe etọ lori ọrọ Ipinlẹ Iwọ Orun, ki o tu ofin pajawiri ka, ki o paṣẹ ki gbogbo Ipinlẹ na d i b o lati yan awọn ti nwọn fẹ sori aga Ijọba.

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti nwọn ha nib ẹlẹha-apapandodo ... ni nwọn wa ninu inira pupọ; nwọn ko raye lọ si ibiṣẹ wọn, bẹ Ijọba ko si s a n epinni owo onjẹ fun ẹnikan ninu wọn.

---

## Nkurumah

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Idajọ-ododo. Ẹsun ti nwọn fi Minisita na sun ni pe o ti fi igba kan kọle ori ẹgbẹdọgbọn pọnun (£5,000) ki o to tun lọ fi ẹgbarun pọnun (£10,000) kọ ile miran; nwọn ni on nikan kọ ni nwọn d'aiye fun, gbogbo awọn lebira oṣiṣẹ ni nwọn wa ninu ti nwọn ko ri ile ti o yẹ ọmọ enia gbe rara.

Bi a ti nkọ iwe yi lọwọ ni a tun ri waya gba lati ọdọ onirohin wa lati ilu Ghana lori ana pe Dokita Nkrumah ti bẹrẹsi gba awẹ lori ọrọ na, o si tun paṣẹ wipe ki nwọn tun sọ igba enia (200) miran s ja ile lori ọrọ wipe nwọn fẹ pa on nwọn ko pa on yi.

## O Fe Bige

(O bere loju ewe kini)

o ni agbẹjọro na ko tilẹ ni etọ lati wa ṣe iṣẹ agbẹjọro nibẹ nitoripe on (Okorodudu) yi na n i a w ọ n Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun ran lọ ṣe Aṣoju wọn n i ilu Oyinbo ti o nṣe iṣẹ lakoko ti n w ọ n n ṣ e i w a d i rẹ lọwọ yi.

---


## LAGOS RACE CLUB

### October Meeting 1962

Saturday 29th, September 6th, 13th & 20th October, 1962.

Provisional Programme a n d Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos. NOTE—No Entry fees w i l l be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday, September 10, 1962.

No Entry will be accepted from a n y horse owner unless his Stable Rent in arrear is paid.

No Cheque will be accepted.

**C. H. E. MILLER.**
Hon. Secretary.



## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR

(a) "C" WAREHOUSE, APAPA QUAY

(b) "D" WAREHOUSE, APAPA QUAY

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at "C" and "D" Warehouses, Apapa Quay.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority for each warehouse separately and returned in sealed envelopes maked "CONFIDENTIAL — TENDER FOR LABOUR "C" (or "D" as the case may be) WAREHOUSE" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of Monday, 17th September, 1962.

3. Tenderers may tender for either one or both of the two warehouses.

4. Persons tendering for "C" Warehouse must use the Form of Tender bearing "C" Warehouse and persons tendering for "D" Warehouse must use the Foorm of Tender bearing "D" Warehouse.

5. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10 for each warehouse, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quay. The deposit will be returned on receipt of a bona fide tender.

6. Only applications from labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

7. Applicants wishing to view either "C" or "D" Warehouse or both before submitting tenders should apply in person to Chief Traffic and Commercial Manager, Apapa Quay.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 761
30th August, 1962.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 24 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23170 EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE 15, Kosoko St., Lagos.